*Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àinípẹ̀kun. Àmín.*

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

## Kíló kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣ́ọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ tí o ti lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

**DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL**
*~ À ń tan Ìhìnrere Káàkiri Aiyé*

**www.divineliterature.org**
**www.doveletters.org**

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023



# A Grande Fuga

**Ǹjẹ́ o mọ̀ bí?** Gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ rẹ, títí dé èyí tí ó kéré jùlọ ló wà nínú àkọsílẹ̀ Ọlọ́run, bí ìwọ kò bá tíì gba Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà rẹ. Àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ ṣì wà ní kíkọ sílẹ̀ ní ọ̀dọ̀ Rẹ̀; ìwọ yóò sì gba ìdájọ́ fún àwọn ẹ̀ṣẹ̀ náà tí ohunkóhun bá ṣelẹ̀, tí o sì ṣàdédé kúrò láiyé yìí, láìjẹ́ pé o jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún Krístì. Rántí pé, a kò ṣèlérí ọ̀la fún ẹnikẹ́ni!

Ọlọ́run kórìíra ẹ̀ṣẹ̀, yóò sì dá ẹ lẹ́jọ́ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ. Ní báyìí, àwọn ẹlẹ́ṣẹ̀ wà ní ipò àìní àjọṣe pẹ̀lú u Rẹ̀. Òun yóò sì sọ wọ́n sínú adágún iná aiyéraiyé, nígbẹ̀yìngbẹ́yìn - níbi tí wọ́n yóò máa joró tọ̀sán tòru, títí láí. Ìdájọ́ tí wọ́n máa gbà nìyí

*Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àinípẹ̀kun. Àmín.*

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

Kíló kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣ́ọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ tí o ti lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL
~ À ń tan Ìhìnrere Káàkiri Aiyé

www.divineliterature.org
www.doveletters.org

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023



A Grande Fuga

Ǹjẹ́ o mọ̀ bí? Gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ rẹ, títí dé èyí tí ó kéré jùlọ ló wà nínú àkọsílẹ̀ Ọlọ́run, bí ìwọ kò bá tíì gba Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà rẹ. Àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ ṣì wà ní kíkọ sílẹ̀ ní ọ̀dọ̀ Rẹ̀; ìwọ yóò sì gba ìdájọ́ fún àwọn ẹ̀ṣẹ̀ náà tí ohunkóhun bá ṣelẹ̀, tí o sì ṣàdédé kúrò láiyé yìí, láìjẹ́ pé o jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún Krístì. Rántí pé, a kò ṣèlérí ọ̀la fún ẹnikẹ́ni!

Ọlọ́run kórìíra ẹ̀ṣẹ̀, yóò sì dá ẹ lẹ́jọ́ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ. Ní báyìí, àwọn ẹlẹ́ṣẹ̀ wà ní ipò àìní àjọṣe pẹ̀lú u Rẹ̀. Òun yóò sì sọ wọ́n sínú adágún iná aiyéraiyé, nígbẹ̀yìngbẹ́yìn - níbi tí wọ́n yóò máa joró tọ̀sán tòru, títí láí. Ìdájọ́ tí wọ́n máa gbà nìyí

(Romu 6:23, Ìwé Ìfihàn 20:15), ṣùgbọ́n Ìròhìn Rere wà. Ọlọ́run kò fẹ́ kí ẹnikẹ́ni ṣègbé. Ó pèsè ọ̀nà fún ọ láti rí ìdáríjì ẹ̀ṣẹ̀ gbà, kí o lè yè bọ́ gbígbé ìgbésí aiyé tí ó kún fún ìbànújẹ́, àti ìdájọ́ ìkẹyìn Rẹ̀ tí yóò wá pẹ̀lú ìbínú àti òdodo. Ọ̀nà yìí ni Ẹ̀bùn Ìgbàlà tí Ó fún gbogbo aráiyé nípasẹ̀ Ọmọ Rẹ̀, Jésù Krístì (Jòhánù 3:16). Ẹ̀jẹ̀ Jésù tí Ó ta sílẹ̀ lórí igi Àgbélébùú Kálfárì ń wẹ gbogbo onírúurú ẹ̀ṣẹ̀ mọ́ - yálà Ìbọ̀rìṣà, ìpànìyàn, olè jíjà, àgbèrè, panṣágà, iró pípa, ìmutípara, tabi ṣíṣe iṣẹ́ oṣó àti àjẹ́; àti àwọn ẹ̀ṣẹ̀ mìíràn tí o lè ronú kàn. Kò sí ẹ̀ṣẹ̀ tí ó burú ju òmíràn lọ ní ojú Ọlọ́run. Ní àfikún, Krístì kìí kọ ẹnikẹ́ni tí ó bá wá sí òdọ̀ Rẹ̀ fún ìgbàlà, ẹ̀ṣẹ̀ yòówù tí wọ́n dá (Jòhánù 6:37).

Ẹ̀ṣù yóò gbìyànjú láti jẹ́ kí o gbàgbọ́ pé o kìí ṣe ẹni tí ó yẹ láti rí àánú Ọlọ́run gbà, nítorí ìwà àìtọ́ tí o ti hù. Má ṣe gbà á gbọ́. Gbàrà tí o bá ti ronúpìwàdà àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ, tí o sì gba Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà rẹ, àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ ti ní ìdáríjì, wọ́n sì ti di ohun ìgbàgbé lọ́dọ̀ Ọlọ́run. Ìwọ yóò di olóododo nígbà náà, o kò sì jẹ̀bi àwọn ẹ̀ṣẹ̀ wọ̀nyẹn mọ́ ní ojú Ọlọ́run nítorí Jésù ti san gbèse gbogbo rẹ̀ lórí àgbélébùú; àti pé, o ti di ẹ̀dá tuntun (2 Kọ́ríńtì 5:17).

Ṣé kò wá jẹ́ ohun ìyanu pé Ọlọ́run fún wa ní Ọmọ Rẹ̀ kanṣoṣo láti jẹ́ ọ̀nà àbáyọ ìdájọ́ amúbíiná tí ó tọ́ sí wa, bí? Ní báyìí, àìṣètọ́ tí ó burú jùlọ tí o lè ṣe sí ara rẹ ni kí o ṣe ìpinnu láti jìnnà sí Ọlọ́run nítorí ẹ̀ṣẹ̀ tí o dá. Má ṣe jẹ́ kí Sátánì gba ọjọ́ òmìnira mìíràn lọ́wọ́ rẹ, kí ó máa pè ọ́ láti wà nínú adágún iná pẹ̀lú rẹ̀ títí gbére. Ṣe ìpinnu láti ronúpìwàdà àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ, kí o sì jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún Jésù Krístì, lónìí.

## Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì nísinsìnyí?

Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́.
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.
3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.
4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí:

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n: Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti*

(Romu 6:23, Ìwé Ìfihàn 20:15), ṣùgbọ́n Ìròhìn Rere wà. Ọlọ́run kò fẹ́ kí ẹnikẹ́ni ṣègbé. Ó pèsè ọ̀nà fún ọ láti rí ìdáríjì ẹ̀ṣẹ̀ gbà, kí o lè yè bọ́ gbígbé ìgbésí aiyé tí ó kún fún ìbànújẹ́, àti ìdájọ́ ìkẹyìn Rẹ̀ tí yóò wá pẹ̀lú ìbínú àti òdodo. Ọ̀nà yìí ni Ẹ̀bùn Ìgbàlà tí Ó fún gbogbo aráiyé nípasẹ̀ Ọmọ Rẹ̀, Jésù Krístì (Jòhánù 3:16). Ẹ̀jẹ̀ Jésù tí Ó ta sílẹ̀ lórí igi Àgbélébùú Kálfárì ń wẹ gbogbo onírúurú ẹ̀ṣẹ̀ mọ́ - yálà Ìbọ̀rìṣà, ìpànìyàn, olè jíjà, àgbèrè, panṣágà, iró pípa, ìmutípara, tabi ṣíṣe iṣẹ́ oṣó àti àjẹ́; àti àwọn ẹ̀ṣẹ̀ mìíràn tí o lè ronú kàn. Kò sí ẹ̀ṣẹ̀ tí ó burú ju òmíràn lọ ní ojú Ọlọ́run. Ní àfikún, Krístì kìí kọ ẹnikẹ́ni tí ó bá wá sí òdọ̀ Rẹ̀ fún ìgbàlà, ẹ̀ṣẹ̀ yòówù tí wọ́n dá (Jòhánù 6:37).

Ẹ̀ṣù yóò gbìyànjú láti jẹ́ kí o gbàgbọ́ pé o kìí ṣe ẹni tí ó yẹ láti rí àánú Ọlọ́run gbà, nítorí ìwà àìtọ́ tí o ti hù. Má ṣe gbà á gbọ́. Gbàrà tí o bá ti ronúpìwàdà àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ, tí o sì gba Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà rẹ, àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ ti ní ìdáríjì, wọ́n sì ti di ohun ìgbàgbé lọ́dọ̀ Ọlọ́run. Ìwọ yóò di olóododo nígbà náà, o kò sì jẹ̀bi àwọn ẹ̀ṣẹ̀ wọ̀nyẹn mọ́ ní ojú Ọlọ́run nítorí Jésù ti san gbèse gbogbo rẹ̀ lórí àgbélébùú; àti pé, o ti di ẹ̀dá tuntun (2 Kọ́ríńtì 5:17).

Ṣé kò wá jẹ́ ohun ìyanu pé Ọlọ́run fún wa ní Ọmọ Rẹ̀ kanṣoṣo láti jẹ́ ọ̀nà àbáyọ ìdájọ́ amúbíiná tí ó tọ́ sí wa, bí? Ní báyìí, àìṣètọ́ tí ó burú jùlọ tí o lè ṣe sí ara rẹ ni kí o ṣe ìpinnu láti jìnnà sí Ọlọ́run nítorí ẹ̀ṣẹ̀ tí o dá. Má ṣe jẹ́ kí Sátánì gba ọjọ́ òmìnira mìíràn lọ́wọ́ rẹ, kí ó máa pè ọ́ láti wà nínú adágún iná pẹ̀lú rẹ̀ títí gbére. Ṣe ìpinnu láti ronúpìwàdà àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ, kí o sì jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún Jésù Krístì, lónìí.

Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì nísinsìnyí?

Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́.
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.
3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.
4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí:

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n: Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti*